# OFIN ATỌWỌDỌWỌ ENIYAN TABI OFIN ỌLỌRUN?
## Matteu 15:1-20

## ẸKỌ 95 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Nitori lati inu ọkàn ni iro buburu ti ijade wá, ipania, panṣaga, àgbere, olè, ẹ̀ri eke, ati ọ̀rọ buburu" (Matteu 15:19).**

**I Ẹ̀sùn Awọn Akọwe ati Farisi**

1. Wọn fi awọn ọmọ-ẹyin sùn pé wọn n rú ofin atọwọdọwọ awọn alagba, Matteu 15:1, 2
2. Awọn Farisi n fi ofin atọwọdọwọ wọn rú ofin Ọlọrun, Matteu 15:3
3. Oluwa pa a laṣẹ pe ki a bu ọla fun awọn obi wa, Matteu 15:4-6; Ẹksodu 20:12; Deuteronomi 5:16; Owe 23:22; Efesu 6:2
4. Wọn n fi ètè wọn bu ọlá fun Ọlọrun, ki i ṣe ọkàn wọn, Matteu 15:7, 8; Isaiah 29:13
5. Awọn Farisi n fi ofin eniyan kọ́ ni lẹkọọ, Matteu 15:9; Kolosse 2:20-22

**II A Ṣe Alaye Ohun ti N Sọni Di Aimọ́**

6. Jesu pe ijọ eniyan lati gbọ́ ọ̀rọ Rẹ̀, Matteu 15:10
7. Ki i ṣe ohun ti o wọ ẹnu lọ ni o n sọ eniyan di alaimọ́, Matteu 15:11; Titu 1:15
8. Awọn ọmọ-ẹyin sọ fun Jesu pe inu bi awọn Farisi, Matteu 15:12
9. Igikigi ti Oluwa kò bá gbìn, a oo fàátu kuro, Matteu 15:13; 1 Kọrinti 3:13

**III Awọn Afọju Amọna**

10. Bi afọju ba n ṣe amọna afọju, awọn mejeeji ni yoo ṣubu sinu kòtò, Matteu 15:14; Isaiah 9:16; Malaki 2:8
11. Peteru beere pe ki Jesu tumọ òwe naa fun wọn, Matteu 15:15, 16
12. Jesu ṣe alaye pe ohun ti o jade lati inu ọkàn ni o n sọ eniyan di alaimọ́, Matteu 15:17-19; Jakọbu 3:6; Gẹnẹsisi 6:5
13. Ọwọ́ ti a kò wẹ̀ kò lè sọ ni di alaimọ́, Matteu 15:20

## ALAYE

### Ofin Atọwọdọwọ

Awọn akọwe ati Farisi tẹnu mọ́ ofin atọwọdọwọ gidigidi, wọn wi pe o jẹ ofin ti a kò kọ silẹ, eyi ti Ọlọrun sọ fun Mose lori Oke Sinai ti a si ti ẹnu sọ lati iran kan fun iran miiran. Dajudaju bi iran kan ti n tẹle ekeji ni wọn fi àṣa ati ero miiran kún un, awọn Farisi ti wọn si jẹ́ alaṣeju nipa ọrọ ofin, kò ni imọ ẹmi lati ri i pe iwe a maa pani ṣugbọn ẹmi ni n sọ ni di alaaye. Ile-isin pupọ wa sibẹ lonii ti wọn gbé eto, ati ohun ode ara miiran ga rekọja Ọrọ Ọlọrun.

Jesu ti n ṣe iṣẹ iyanu pupọ kaakiri Okun Galili. Nibikibi ti O ba lọ, i baa ṣe abule, ilu kekere, tabi arin igboro ilu, wọn a gbé abirun tọ Ọ wá, wọn a si bẹ Ẹ ki wọn ki O le fi ọwọ́ kan iṣẹti aṣọ Rẹ̀, iye awọn ti o ba si fọwọ kan an ri imularada (Marku 6:56). Eṣu ni awọn iranṣẹ rẹ̀ ti i maa fi igba gbogbo sun ẹ̀sùn èké, ṣe atako, wọn a si gbiyanju lati bi igbagbọ awọn ẹlomiran ṣubu. A ri nihin bi ó ti rán awọn akọwe ati awọn Farisi jade lati Jerusalẹmu wá fun ṣiṣe ariwisi kan naa. Wọn kò pé ri ẹ̀sun kan lọ mọ́. Awọn ọmọ-ẹyin n jẹun lai wẹ ọwọ́ wọn, eyi ti o lodi si ofin atọwọdọwọ awọn alagba. Jesu mọ ohun ti ó wà lọkan wọn patapata, ati pe ki i ṣe nitori ofin ilera ni wọn ṣe n ka ẹsun si wọn lọrun bikoṣe nitori wọn rú ofin atọwọdọwọ nipa aiwẹ ọwọ́. Jesu bi wọn leere pe, "Ẽṣe ti ẹnyin pẹlu nfi ofin atọwọdọwọ nyin rú ofin Ọlọrun?" (Matteu 15:3). Kò fi itumọ ọrọ Rẹ̀ pamọ fun wọn. O sọ fun wọn ni ti ọ̀kan ninu ofin ti wọn n rú. Oluwa ti sọ fun wọn pe ki wọn bọwọ fun baba ati iya wọn, ṣugbọn ofin ti wọn ti yí ofin Ọlọrun pada, o si mu ki wọn fi ẹbun fun ijọ, ẹbun naa ni ko si ni jẹ ki wọn ṣe ojuṣe wọn fun awọn obi wọn. A ri i pe lonii awọn eniyan ti lọ jinna ju bẹẹ lọ kuro ninu ofin Ọlọrun; lai tilẹ jẹ pe wọn fi ẹbun fun ijọ, wọn n fi awọn obi wọn silẹ fun awọn alaanu lati maa tọju wọn.

### Afọju Amọna

Ọrọ ibawi ti o le jù lọ ti Jesu sọ, awọn agabagebe ni O sọ ọ́ sí, awọn ti o n sin lode ara ṣugbọn ti ọkàn wọn kun fun ohun buburu gbogbo. Wọn leti lati fi gbọ́ ṣugbọn wọn ko le gbọ́, wọn ni oju wọn kò le riran -- afọju ti o n ṣamọna afọju. Jesu wi pe, "Ẹ jọwọ wọn si: . . . . awọn mejeji ni yio ṣubu sinu ihò" (Matteu 15:14). Bi o ti n sọ nipa ti awọn ti ko gba ifẹ otitọ ti a ba fi gba wọn là, Paulu wi pe Oluwa yoo rán ẹtan lile si wọn, ki wọn ba le gba eke gbọ́, ki a ba le ṣe idajọ wọn (2 Tẹssalonika 2:10-12). Paulu pẹlu kilọ fun ni ki a ma ṣe feti si itan asan awọn Ju ati ofin eniyan (Titu 1:14). O tun wi pe ki wọn kọ itan awọn agba obinrin silẹ. Dajudaju awọn itan wọnyii jẹ́ ofin atọwọdọwọ ti a ti fi lelẹ fun wọn, wọn kò si bá Ọrọ Ọlọrun mu.

**Ipe si Ijọ Eniyan**

Jesu ké si ijọ eniyan lati gbọ́ ati lati mọ otitọ. Bi o tilẹ ṣe pe awọn kan gbọ́ wọn kò si naani, sibẹ Oluwa fẹ ki gbogbo eniyan gbọ́. Ọrọ naa sọ fun ni pe ki a jẹ oluṣe Ọrọ naa, ki a má ṣe jẹ́ olugbọ nikan. Awọn Farisi wọnyii wa ọwọ́ mọ́ ododo ara wọn koko, wọn ko si bikita fun ododo ti o ti ọdọ Ọlọrun wá lati Ọrun. A gbọdọ ṣọra ki a ma fi iṣẹ rere ti wa dipo ododo Ọlọrun ninujj ọkan wa.

Ihinrere ti o logo yii ni o sọ wá di ẹda titun, ti o si yí ọkàn ti ẹ̀ṣẹ ti bajẹ pada si ọkàn mimọ́ ti o kún fun ododo ati otitọ. Ọkàn titun yii ni Oluwa fẹ́ ki gbogbo wa ní. Ọkàn yii ti a sọ di titun nipa atunbi, yoo gba otitọ yoo si fẹ́ ẹ.

**Lati Inu ni Ibajẹ ti i Wá**

Jesu sọ fun wọn gbangba pe ki i ṣe ohun ti a jẹ ni o n sọ eniyan di alaimọ́, bikoṣe eyi ti o ti ẹnu wa jade ni o n fa idibajẹ wá. Ninu Jeremiah 17:9 a kà pe, "Ọkàn enia kún fun ẹ̀tan jù ohun gbogbo lọ, o si buru jayi! tani o le mọ̀ ọ?" Oluwa dahun pe, Emi, OLUWA, ni iwá awari ọkàn enia, emi ni ndan inu wò' (Jeremiah 17:10). Bi a ba ṣi ọkàn wa paya fun Oluwa, Oun yoo yẹ inu wa wò, Oun o si jẹ ki a mọ̀ bi ipa ọna buburu kan ba wà ninu wa.

**Awọn Farisi Binu**

Awọn ọmọ-ẹyin sọ fun Jesu pe awọn Farisi binu si ọrọ Rẹ̀. Jesu wi pe, "Igikigi ti Baba mi ti mbẹ li ọrun kò ba gbìn, a o fà a tu kuro." Ninu Orin Dafidi 52:3-5, a ka pe "Iwọ fẹ ibi jù ire lọ; ati eke jù ati sọ ododo lọ. Iwọ fẹ ọ̀rọ ipanirun gbogbo, iwọ ahọn ẹ̀tan; Ọlọrun yio si lù ọ bolẹ lailai, yio si dì ọ mu, yio si ja ọ kuro ni ibujoko rẹ, yio si fà ọ tu kuro lori ilẹ alãye."

**Ọmọ-Ẹyin ti Òye Kò Yé**

Nigba ti Peteru bẹ Oluwa pe ki o la òwe naa yé wọn o dabi ẹni pe ẹnu ya Jesu, O si sọ pe, Ẹnyin pẹlu wà li aimoye sibẹ?" Lẹyin naa O là á yé wọn pe ki i ṣe ohun ti o ba wọ ẹnu lọ si inu ni o n sọ eniyan di alaimọ́ bikoṣe ohun ti o ba ti ẹnu jade lati inu ọkàn wá ni o n sọ eniyan di alaimọ́. "Nitori lati inu ọkàn ni iro buburu ti ijade wá, ipania, panṣaga, àgbere, olè, ẹ̀ri-eke, ati ọ̀rọ buburu, ohun wọnyi ni isọ enia di alaimọ́: ṣugbọn ki a jẹun li aiwẹwọ́, kò sọ enia di alaimọ́" (Matteu 15:19, 20). Ọkàn ni orisun iye, ọkàn yii si ni Ọlọrun ni i bá lò. "Jù gbogbo ohun ipamọ́, pa aiya rẹ mọ́; nitoripe lati inu rẹ̀ wá ni orisun ìye" (Owe 4:23). "Nitoripe bi o ti nṣiro li ọkàn rẹ̀, bẹ̃ li o ri" (Owe 23:7). A ri i pe ọkàn ni pataki ohun ti Ọlọrun ni i ba lo. Ẹṣẹ a maa sọ ọkàn di alaimọ́, Ẹjẹ Jesu nikan ni o si le wo ọkàn sàn kuro ninu ẹ̀ṣẹ.

Ẹjẹ naa le wẹ ẹ̀ṣẹ nù kuro patapata tewé tegbò, ki o si sọ ọkàn di funfun laulau. Kò si orisun ti o le mú omi didun ati kikoro jade nibi kan naa (Jakọbu 3:11). Ẹṣẹ a maa mu omíró jade; ọkàn funfun a maa mú omi didun jade wá. "Enia rere lati inu iṣura rere ọkàn rẹ̀ ni imu ohun rere jade wá; ati enia buburu lati inu iṣura buburu ọkàn rẹ̀ ni imu ohun buburu jade wá: nitori lati ọ̀pọlọpọ ohun ọkàn li ẹnu rẹ̀ isọ" (Luku 6:45). Ki a jẹ ounjẹ lai wẹ ọwọ́ kò sọ eniyan di alaimọ́, ṣugbọn ọkàn ẹ̀ṣẹ a maa mú idibajẹ wá.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ofin atọwọdọwọ?
2. Ẹ̀sùn wo ni awọn Farisi fi awọn ọmọ-ẹyin sùn?
3. Ìfisùn wo ni Jesu fi awọn Farisi sùn?
4. Ki ni o sọ eniyan di alaimọ́?
5. Nibo ni Jesu sọ pe aimọ́ ti n wá?
6. Bawo ni a ti le ṣe ki a má di alaimọ́?
7. Bi afọju ba n fọna han afọju, ki ni yoo ṣẹlẹ?
8. Ki ni yoo ṣẹlẹ si igikigi ti Baba wa ti n bẹ lọrun kò bá gbìn?